# BÍRÍKÌ LAI SI KORIKO

## Ẹksodu 5:1-23

## ẸKỌ 50 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Oju OLUWA mbẹ lara awọn olododo, eti rẹ̀ si ṣí si igbe wọn" (Orin Dafidi 34:15).**

**I Ifarahàn Mose ati Aarọni niwaju Farao**

1 Awọn Ọmọ Israẹli bẹbẹ fun aye lati lọ sin Ọlọrun, wọn si lo Ọrọ Oluwa gẹgẹ bi aṣẹ wọn, Ẹksodu 5:1; 3:12, 13

2 Farao ni oun kò mọ ẹni ti Ọlọrun i ṣe o si kọ̀ lati gbọran si ọrọ Rẹ̀, Ẹksodu 5:2; 3:19

3 Mose ati Aarọni tun beere lẹẹkan si i, Ẹksodu 5:3; 2 Peteru 3:9

4 Farao ba Mose ati Aarọni sọ̀ pe wọn n di iṣẹ awọn Ọmọ Israẹli lọwọ, Ẹksodu 5:4, 5; 1:7-9; Orin Dafidi 105:24

**II A fi Kun Ẹru Wuwo awọn Ọmọ Israẹli**

1 Farao paṣẹ onrorò, ninu iṣọtẹ si Ọlọrun, Ẹksodu 5:6-9; Owe 14:31; Oniwasu 3:16, 17; Orin Dafidi 37:12-17, 35, 36

2 Awọn akoniṣiṣẹ Egipti mu aṣẹ naa ṣẹ, Ẹksodu 5:10-13

**III Irahun Awọn ti a n Ṣẹ Niṣẹ**

1 Iṣoro iṣẹ naa mu ijiya ba awọn olori awọn Ọmọ Israẹli, Ẹksodu 5:14; Oniwasu 5:8

2 Awọn olori naa sọ iṣoro wọn fun Farao, Ẹksodu 5:15, 16

3 Farao jingiri sinu iwa-ikà rẹ̀, Ẹksodu 5:17-19

4 Awọn olori ti a n pọ́n loju wọnyii bá Mose ati Aarọni sọ̀ lori ọran yii, Ẹksodu 5:20, 21

5 "Mose si pada tọ OLUWA lọ," Ẹksodu 5:22, 23; 32:11-14; Numeri 11:11-15

## ALAYE

Yoo ṣoro fun wa lati le moye tabi mọ rirì bi Mose ti jẹ eniyan nla to, ayafi bi a ba ṣe afiyesi iwa rẹ̀ ni oriṣiriṣi ọ̀na gẹgẹ bi ọjọgbọn eniyan ati darandaran, aṣaaju ati aṣòfin, jagunjagun ati òṣèlú, ogboju akọni ninu ija, sibẹ sibẹ ti o jẹ ọlọkan tutu ju lọ ninu gbogbo eniyan. Iṣẹ̀lẹ̀ kọọkan ninu itan igbesi-aye rẹ ni o n kọ́ wa ni ẹ̀kọ́ titun ti o si ṣe iyebiye.

A ri bi o ti yara lati yi pada kuro ninu ọna ti rẹ̀ lati gbọ́ ohùn Oluwa nibi ti igbẹ ti n jó, sibẹ wo bi o ṣe jẹ pe eku-káká ni o fi gba ipo nla ti a fi fun un nibẹ. Ohun ti o fa aifẹ tete gbà yii ni lati jẹ pe nitori titobi iṣẹ ti a yàn fun un yii ati bi o ṣe fẹrẹ daju gbangba pe Farao yoo kọ̀ lati gbà ẹbẹ fun Israẹli nigba ti a ba sọ fun un. Ṣugbọn Mose gbọran, a si ri i nisisiyii ninu aafin ọba ti o n ṣipẹ fun awọn eniyan ti a n ni lara yii.

Gbogbo awọn ọba Egipti ni a maa n pe ni Farao pẹlu orukọ ti wọn n jẹ tẹlẹtẹlẹ. A maa n lo orukọ yii bẹẹ ni ọna ti awa naa n gba lo orukọ ọba tabi ọmọ-alade. Ṣugbọn ọna miiran wa ti o le mu ki awọn eniyan yii yan orukọ yii. Ni itumọ rẹ̀, eyi n tọka si ọ̀ni, eyi ti o jẹ ẹranko ti wọn n sìn laaarin awọn ara Egipti, fifi kún ti a si fi orukọ ọ̀wọ̀ yii kun orukọ alakoso le jẹ lati mu ki o le já si ẹni ti wọn o maa fi ọ̀wọ̀ ati itẹriba fun.

Ni ilẹ Egipti awọn eniyan maa n sin ọpọlọpọ oriṣa. Awọn ohun ti a n hú jade ninu ilẹ nibẹ tubọ n mu ki a maa ri ọpọlọpọ kún ọpọlọpọ awọn oriṣa ti wọn n sin. Wọn rò pe olukuluku orilẹ-ede ni o ni ọlọrun ti n ṣe amọna rẹ̀, ati pe awọn ni o n pinnu bi ọlọrun kọọkan ti ṣe pataki tó laaarin ẹgbẹẹgbẹrun awọn ọlọrun ti wọn ro pe o wà, nipa eyi ti wọn n ṣe akiyesi bi awọn eniyan orilẹ-ede ti o ni ọlọrun naa ti lagbara to. Niwọn igba ti o jẹ pe Egipti nigba naa jẹ orilẹ-ede alagbara ti n ṣakoso ayé nigba naa, ti o si n ṣakoso ọpọlọpọ ọrọ̀ agbaye, ti o si jẹ olori fun ọpọlọpọ aimoye ẹrú ati awọn eniyan ti a ti tẹri wọn ba, wọn gbà pe awọn oriṣa Egipti ni ọlọrun ti o lagbara ju lọ.

Mose ati Aarọni fara hàn niwaju Farao ni orukọ Oluwa Ọlọrun Israẹli, wọn si beere pe ki a fun Israẹli ni ayè lati lọ si iju lati sin ati lati rubọ si Ọlọrun wọn, Jehofa. Ṣugbọn Farao kò bu ọlá fun Ọlọrun Israẹli. O ni ogunlọgọ awọn oriṣa ti o n sin ti o si rò pe wọn tobi ju Jehofa ti Israẹli lọ, o si daju pe o ti rò ninu ọkàn rẹ pe Ọlọrun awọn eniyan ti a rẹ̀ silẹ, ti a si n pọ́n loju bayii bi awọn Heberu, kò le jẹ Ọlọrun Alagbara kan tabi Ẹni ti iru alaṣẹ nla bi ti oun gbọdọ bu ọlá fun. Idahun rẹ ni, "Tali OLUWA, ti emi o fi gbà ohùn rẹ̀ gbọ́ lati jẹ ki Israẹli ki o lọ? Emi kò mọ̀ OLUWA na, bẹ̃li emi ki yio jẹ ki Israẹli ki o lọ." Ṣugbọn Ọlọrun ti fun Mose ni idaniloju nigba ti o duro niwaju igbẹ ti n jó, pe Israẹli yoo wá sin Oun ni ibẹ naa, nitori eyi Mose mọ̀ pe Ọlọrun yoo mu Ọrọ Rẹ̀ ṣẹ.

Lati atetekọṣe ti eniyan ti dẹ́ṣẹ̀, ni Ọlọrun ti n beere irubọ́, A si maa tẹwọgba a nigba ti a ba ṣe e pẹlu igbagbọ́; ko si iṣẹ isin tabi eto isin ti o ṣe itẹwọgba niwaju Rẹ̀ lai si irubọ. Niwọn igba ti o fẹrẹ jẹ pe gbogbo ẹranko ni awọn ara Egipti maa n sin, yoo ṣoro lati fi awọn ẹran wọnyii ṣe irubọ ni Egipti nitori wahala ti eyi yoo fà.

Apa kan ninu maluu ati agbo ẹran ni lati bá Israẹli lọ ki wọn ba le yàn ninu rẹ̀ fi ṣe irubọ; niwọn igba ti awọn ara Egipti ti i maa fi oju tẹmbẹlu awọn darandaran gẹgẹ bi awọn eniyan ti o n ṣe iwọsi si awọn ọlọrun Egipti, ko ṣe e ṣe pe ki awọn Ọmọ Israẹli fi itọju iyoku awọn ẹran wọn le awọn ara Egipti lọwọ nigba ti awọn Ọmọ Israẹli ko ba si nile. Ko si ẹni kan ninu awọn Ọmọ Israẹli ti a gbọdọ fi silẹ lati maa ṣe itọju ẹran nitori gbogbo wọn ni Oluwa ti paṣẹ fun lati lọ sin Oun. Ohun ti o n gbé wọn jade lọ hàn gbangba. Ọrọ pe a n gbọjẹgẹ tabi gba ẹbẹ ko tilẹ le bọ si i rara. Gbogbo aṣẹ Oluwa ni ṣiṣẹ; gbogbo maluu, agbo-ẹran, ati eniyan ni o ni lati lọ.

Gẹgẹ bi Ọlọrun ti sọ tẹlẹ, Farao kọ̀ lati fun wọn laayè. Ṣugbọn imọtẹlẹ Ọlọrun nipa ipinnu ọba agberaga yii ko gba agbara kuro lọwọ rẹ lati ṣe eyi ti o wu u. Farao yàn ipa ọna ti rẹ̀ o si sé ọkàn rẹ̀ le si Ọlọrun; nitori o mọọmọ yàn lati ṣe bẹẹ, Ọlọrun gba a laye lati ṣe eyi ti o yàn. Farao ba Mose ati Aarọni sọ̀ pe wọn dá rúgudu silẹ laaarin awọn Ọmọ Israẹli eyi ti o fa idiwọ wá ninu iṣẹ wọn, o si paṣẹ fun Israẹli lati pada si idi iṣẹ wọn; alaṣẹ onroro bi ti rẹ̀ nikan ni o le fi kun iṣẹ awọn Ọmọ Israẹli ni iru akoko bayii.

"Ẹnyin kò gbọdọ fun awọn enia na ni koriko mọ́ lati ma ṣe briki" fi ẹrù ti o wuwo rekọja kun ẹrù ti o n wọ̀ wọ́n lọrun tẹlẹtẹlẹ; ṣugbọn aṣẹ ni ti a tun pa wi pe "ati iye briki ti wọn ti ima ṣe ni igba atẹhinwa, on ni ki ẹnyin bù fun wọn; ẹnyin kò gbọdọ ṣẹ nkan kù kuro nibẹ" mu ki iṣẹ naa já si eyi ti ko ṣe e ṣe. Awọn olori awọn Ọmọ Israẹli fi ẹsun sun Farao lẹyin ti a ti lu wọn ni ilù iyà ti wọn ko si ṣaanu fun wọn, sibẹ aṣẹ onrorò ti o ti pa tẹlẹ naa ni o tun pa pe nitori wọn fẹ ṣe ọlẹ ni wọn ṣe n ro ero ti ko ni laari loju rẹ pe wọn fẹ lọ sin Ọlọrun wọn.

Awọn awadi ohun laelae ti fi idi ọrọ awọn Ọmọ Israẹli ninu ori ẹkọ yii mulẹ pe otitọ ni. Ninu ahoro ọkan ninu awọn ile ti o wà ni Egipti ni igba laelae, eyi ti o dabi ile kiko-nnkan-pamọ-si, awọn biriki ti isalẹ ti a to daradara ni a ri pe a fi koriko ti o pọ̀ sinu rẹ̀, eyi ti o di awọn biriki ti a fi oorun sun jinna yii mu mọra wọn. Awọn biriki ti agbedemeji ko ni koriko ti o pọ̀ ninu wọn, eyi si jẹ koriko iru miiran ti a wú ti gbongbo ti gbongbo. Awọn ogiri ti oke tabi biriki ti o kẹyin si oke iye yii ni a fi kiki biriki ṣe, ko si ẹyọ koriko kan ṣoṣo ninu rẹ rara. Eyi yii duro gẹgẹ bi ẹri ipọ́n-ni loju ati fifi ipá tẹri ẹni ba ti ko ni afiwe fun ọpọlọpọ ọdun lẹyin eyi.

Awọn Ọmọ Israẹli wa ri i pe ẹru naa wuwo ju eyi ti wọn le fara da lọ. Awọn olori wọn ba Mose ati Aarọni sọ̀, wọn si pe Ọlọrun ki o ṣe idajọ wọn nitori kikuna ti o dabi pe igbiyanju wọn kuna nipa ohun ti wọn ṣe lati dá Israẹli silẹ bi o ti ri yii. Boya inu awọn Ọmọ Israẹli bajẹ pupọ fun aasiki ati ọrọ̀ awọn ẹlẹṣẹ ati abọriṣa orilẹ-ede Egipti yii, ati ipo titẹ̀-lori-ba ati oṣi ti awọn wà. Ọlorun ti ṣeleri lati bukun Israẹli ati lati gegun fun awọn ti o ba fi awọn eniyan Rẹ̀ ré; ṣugbọn ibukun yii tabi ẹgun naa kò si ti i fara hàn titi di isisiyii. Ko si ohun miiran ti wọn le ri nisisiyii gẹgẹ bi wọn ti n fi oju ti ẹ̀dá wo iwaju, ju ọpọlọpọ ọdun ninu iṣẹ lile gẹgẹ bi ẹrú, titi di igba ti kiki ikú ti wọn n reti yoo mu un wá si opin.

Ọpọlọpọ igba ni o wà ninu igbesi-aye Israẹli nigba ti iṣoro nla nla doju kọ Mose eniyan Ọlọrun yii. Eyi jẹ ọ̀kan. Ṣe akiyesi bi o ti ṣe nigba ti a doju kọ ọ pẹlu ẹsun ti o wọ ni lara yii, lẹyin ti o ti fi otitọ ṣe gbogbo ohun wọnni ti Ọlọrun paṣẹ fun un lati ṣe. Awọn ọrọ diẹ ninu Iwe Mimọ sọ fun wa nipa Orisun nla nì ti Mose tọ̀ lọ ni ọpọlọpọ igba iṣoro bi iru eyi: "Mose si pada tọ̀ OLUWA lọ." Nipa bayii Mose ni idaniloju lati mọ ọna ti oun yoo tọ̀. Ko le ṣe aṣiṣe nigba ti o tọ Oluwa lọ fun iranlọwọ. Oluwa ko ja a tilẹ ri, bakan naa ni Oun ki yoo ja wa tilẹ! Nigba gbogbo ni ọna kan yoo la laarin okun ati ọna kan laarin ibu, bi awa pẹlu, bi i ti Mose, yoo ba pada tọ Oluwa lọ nigba ti itanṣan oorun n ràn tabi nigba ti iji n ja!

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni oju rere ti Mose ati Aarọni beere lọwọ Farao ni akoko yii?

2 Ki ni ohun ti wọn sọ gẹgẹ bi idi rẹ̀ ati aṣẹ wọn lati beere?

3 Ki ni idahun Farao?

4 Njẹ Mose ha mọ tẹlẹ iru iwa ti Farao yoo hù?

5 Ki ni ẹ̀sun ti Farao fi kan Mose ati Aarọni?

6 Ki ni idi ti Farao sọ pe awọn Ọmọ Israẹli ṣe n beere lati lọ sin Ọlọrun?

7 Ki ni ihà ti Farao kọ si Ọlọrun awọn Ọmọ Israẹli?

8 Ṣe alaye aṣẹ ti Farao pa.

9 Ki ni abajade aṣẹ yii lori awọn olori Israẹli?

10 Ki ni Mose ṣe nigba ti awọn Ọmọ Israẹli sọ ẹ̀dùn wọn fun un?